# Christ Apostolic Miracle Ministry Sunday School

**Ose kerinlelogbon: Osu Kejo Ojo kokanlelogun, 2016**

**Akori Oro: Idapo pelu Olorun** – Apa kini

**Eko kika: 2 Korinti 6: 11-16**

## Afihan

Idapo je iwajowa larin awon enia ti won jijo ni ife si ohun kanna tabi ti won nse nkan lapapo bi awujo. A si tun le wipe idapo ni ikorajo-po awon enia ti won jijo nle ohun kanna tabi ni iriri kanna.
A ko sinu bibeli wipe, idi ti a fi da awa eda-enia ni lati ma se ise Olorun **Genesisi 2: 15**. Torina, a ni lati ni idapo pelu eleda wa, ki a ba le se aseyori ninu ise-emi ti a nse ni ile alaaye.

Enikeni ti ko ba ni idapo pelu Oluwa ti se aigboran si ase Olorun, iru awon enia be ko le gbadun awon anfani ti a fifun awon ti won ni idapo pelu Olorun. Awon anfani ti Olorun ti pese sile fun awon okan ti o ni idapo pelu re ni awon wonyi:

- Ise iyanu logan/lesekese
- Ao yanju isoro aiye won
- Ao se atunse aiye won, besini ao mu pada bo sipo
- Igbega ninu ara ati emi

Awon ona meji pataki yi ni a fi le ni idapo pelu Olorun:

1. Orin kiko, iwasu, adura ati awe
2. Onje ale Oluwa

Ki idapo yi to le waye, o ni lati beru Oluwa ki o si gboran si lenu, nipa mimu ofin re se ati titele awon ase re. Ni igbayi ni o le je ore Olorun, ti enyin mejeji yio si jijo ni ife ohun kanna ti nse ijere-okan sinu ijoba re.

## Ti Olorun Ni Ago-ara Re

Olorun da eda-enia ni aworan ara re, nitori ki a le lo ago-ara wa ati emi wa lati sise fun Oluwa, lati fi josin fun Oluwa ati lati ni idapo pelu re. Olorun fe ki a lo ago-ara wa ni ona ti o to, ti o si se itewogba lati se ife re; kise lati fi mu ipinnu tabi ife-okan Esu se.

**Awon ohun ti o ba ofin mu sugbon ti ko ran aiye enia lowo:** Ni ode oni, opolopo nkan ni o ba ofin mu ni awujo wa tabi orile-ede wa; egbagbeje enia ni won si nse

awon nkan wonyi, nitoripe ko lodi si ofin ile won. E jeki nso fun yin, toripe iwa re ati awon ohun ti o nse ko lodi si ofin orile-ede tabi agbegbe re ko tumo si wipe o se itewogba niwaju Oluwa.
Paulu soro nipa nkan wonyi, wipe "ohun gbogbo ni o ye fun mi, sugbon ki se ohun gbogbo ni o li ere: ohun gbogbo ni o ye fun mi, sugbon emi ki yio je ki a fi mi sabe agbara ohunkohun" **1 Korinti 6: 12**. Sora ki awon ohun adidun-aiye maba di o ni igbekun tabi so o di eru won. Mase gba ohunkohun laye lati fi o si abe agbara won tabi joba ninu aiye re. Kiyesara ki awon ohun asan aiye yi ti kole fi igbagbo re mule tabi jeki idapo re pelu Olorun gun-rege (bi o tile ba ofin mu) gba isakoso aiye re **1 Korinti 10: 23**.

**Mase ba ago-ara re je:** Ara mi, e mase ba ago-ara yin je, nitori ara ki se ti agbere, bikose lati lo fun idapo pelu Oluwa; nigbati Oluwa yio si lo ago-ara re ni ona ti o koja oye re **1 Korinti 6: 13**. Nitorina mase ba ago-ara ti o nlo fun idapo pelu Oluwa je nipa agbere ati iwa-eri.
Lo ara re ni ona ti o peye fun idapo pelu Olorun, ki o ma ba fi aye gba ese lati joba ninu ago-ara re tabi fi aye sile fun ifekufe re. Siwajusi, e mase jowo awon eya ara nyin lowo fun ese bi ohun elo aisododo; sugbon e jowo ara nyin fun Olorun, bi alaaye kuro ninu oku, ati awon eya ara nyin bi ohun elo ododo fun Olorun **Romu 6: 12-13**.
Akoko ti to fun o lati fi igbe-aiye ese sile, ki o si bere ajosepo titi-lai pelu eleda re. Mase fun ese ni aye lati gba isakoso aiye re, mase fi aye sile fun ifekufe ti ara; sugbon toju ara re, ki o ma wa ni mimo, ki o si lo ara re fun idapo pelu Olorun.

**Ago-ara re je eya ara Kristi:** Ara ninu Oluwa, eya-ara Kristi li ara wa nse, nje awa o ha mu eya-ara Kristi, ki awa ki o fi se eya-ara agbere bi? Ki a ma ri. Tabi, enyin ko mo pe eniti o ba dapo mo agbere di ara kan? Nitoriti iwe mimo wipe, "awon mejeji yio di ara kan". Sugbon eniti o dapo mo Oluwa di emi kan pelu re **1 Korinti 6: 15-17**. O ku fun o lati se eyiti o dara, se o fe dapo mo agbere ni tabi Oluwa, sugbon mo gbadura wipe eyiti o dara ni iwo yio mu.

**Ago-ara re ni tempili Olorun:** Jeki ago-ara re ti nse tempili Olorun wa ni imototo ni gbogbo igba, gegebi Jesu Kristi ti se afomo tempili ti nbe ni Jerusalemu ni ojo wonni; nigbati o le awon ti nta, ti nra, ti won si nse okowo ninu tempili jade.
Iwe mimo wipe, " enyin ko mo pe tempili Olorun li enyin ise, ati pe Emi Olorun ngbe inu nyin?. Bi enikan ba ba tempili Olorun je, on ni Olorun yio parun; nitoripe mimo ni tempili Olorun, eyiti enyin je"**1 Korinti 3: 16-17**. Ti o ko ba fe ki iparun Oluwa sawari aiye re, mase ba ago-ara re ti nse tempili Olorun je, sugbon yasi-mimo ki o si lo fun idapo pelu Olorun.

Lati akoko yi lo, e ni lati mo wipe ara nyin ni tempili Emi Mimo, ti nbe ninu nyin, ti enyin ti gba lowo Olorun; enyin ki se ti ara nyin mo **1 Korinti 6: 19**.
Ti o ba fe ki Emi Mimo si ma gbe ninu ara re, ki o si ma gbile si, ki o si ma se akoso aiye re; mase si ago-ara re ti nse tempili Olorun, ti o wulo fun idapo pelu eleda re lo.

E jeki o wa ni ookan aiya nyin wipe, Olorun ti ra nyin ni iye kan; Omo re kansoso ti san gbese na ni ori igi agbelebu lati ra araiye pada: nitorina e yin Olorun logo ninu ara nyin, ati ninu emi nyin, ti ise ti Olorun **1 Korinti 6: 20**.
O ki ise ti ara re mo, torina, dake siso oro wipe "ago-ara mi ni, mo le se ohun ti o ba wu mi pelu re". Enikan ti san gbese na nitori re, lati isinyi lo, bere sini se ife eniti o ra o pada pelu eje re. Lo ago-ara re ni ona ti yio te Kristi lorun, ati fun idapo pelu Baba re ti nbe ni orun.

## Mase Ni Idapo Pelu Okunkun

Jesu Kristi wipe "Emi ni imole aiye" **Johannu 9: 5**. Ti Omo ba je imole, eyi tumo si wipe Baba re ti nse Olorun wa je imole pelu. Imole li Olorun wa, okunkun ko si si lodo re rara. Bi awa ba wipe awa ni idapo pelu re, ti awa si nrin ninu okunkun, awa nseke, awa ko si se otito **1 Johannu 1: 5-6**. E mase tan ara nyin je, enia ko le ni idapo pelu Olorun ayafi ti o ba kuro ninu gbigbe ninu okunkun aiye ti o si kehin si ajosepo pelu won.

Niwon igbati enia ko le ma posi ninu ese, ki o wa ma reti ki ore-ofe Olorun ma tesiwaju ninu aiye on. Ti o ba ri be, ko si elese kan ti o le ni idapo pelu Olorun, ayafi ti o ba ronupiwada ti o si ya ara re si mimo **Orin Dafidi 94: 20**.
Oju Oluwa koro si ese, nitorina, Ite tabi ijoba elese ko le ni idapo pelu Olorun tabi je ore re.
E jeki a ma ranti ni igba gbogbo wipe "ibare aiye isota Olorun ni, enikeni ti o ba fe lati je ore aiye di ota Olorun". Iru awon enia be ko le ni idapo pelu Olorun **Jakobu 4: 4**. Ti o ba pinnu lati je ore aiye, o ti so ara re di ota Olorun. Iru enia be ko le ni idapo pelu Olorun, besini Olorun ko le ni idapo pelu iru enia be.
Ni igbati a ba ngbe ninu imole ti a si nrin ninu imole, bi Olorun wa ti nrin ninu imole, igbana ni a ni idapo pelu ara wa, eje Jesu Kristi omo re yio si nwe wa nu kuro ninu ese gbogbo **1 Johannu 1: 7**.

# Christ Apostolic Miracle Ministry Sunday School

**Ose Karundinlogoji: Osu Kejo Ojo Kejidinlogbon, 2016**

**Akori Oro: Idapo pelu Olorun** – Apa keji

**Eko kika: 2 Korinti 6: 11-16**

Ao tesiwaju pelu eko wa, lati ibiti a fi adagba-eko wa ro si. Akori-oro ti o kan ni:

**Ayo ti o wa ninu idapo pelu Olorun**

Enikeni ti o ba ni idapo pelu Olorun yio ni ayo ti a ko le ka tan. Iru awon eda be yio ni ayo ninu okan won, debipe ti awon enia ba kiyesi won, ti won si bere wipe kini ohun na ti nfi ayo kun okan won. Awon wonyi koni le dahun idi kan pato wipe ohun ni nmu inu awon dun, nitoripe ayo lati odo Olorun ni.

**Fi itara ni idapo pelu Olorun:** Oba Dafidi mo ayo ti enia nri nipa idapo pelu Olorun. Idi niyi ti o fi soro nigbati o wa ninu aginju Juda wipe "Olorun, iwo ni Olorun mi; ni kutukutu li emi o ma saferi re; ongbe re ngbe okan mi, eran-ara mi fa si o ni ile gbigbe, ati ile ti npongbe nibiti omi ko gbe si" **Orin Dafidi 63: 1**. Kosi ohun ti iwo yio padanu, sugbon opolopo ere nbe fun o, bi o ba ni idapo pelu Olorun. Nitorina, ni ajose ti o kunna loni pelu eleda re, wa Olorun pelu itara, ki iwo na ba le ni ipin ninu ayo idapo pelu Olorun.

Niwon igbati iriri je oluko pataki, ti Oba Dafidi si mo wipe ayo nbe ninu idapo pelu Olorun; inu re ma ndun ni igbakugba ti won ba wi fun pe, je ki a lo si ile Oluwa lati lo josin, ki a si ni idapo pelu re **Orin Dafidi 122: 1**. E se afarawe oba Dafidi, e ma fi inudidun han ni igbakugba ti akoko bati to lati lo si ile Oluwa. Ni igbakugba ti o ba wa ni Oke-mimo re, josin fun eleda re, se akitiyan lati jeki ilosiwaju ba ohun na ti o so o po mo Olorun; ki ayo idapo pelu Olorun ba le farahan ninu aiye re.

**Imo re nipa Olorun yio di gbigboro:** Olorun wa je aditu-ijinle, ti kosi si eniti o le sawari ogbon re. Ti o ba kepe Olorun lati okan mimo, yio da o lohun, besini yio si fi ohun nla ati alagbara han o, ti iwo ko mo **Jeremiah 33: 3**. Nigbakugba ti o ba ni idapo pelu Olorun, ohunkohun ti o ba bere lodo re, ni yio se fun o. Olorun yio so awon asiri ti iwo ko mo, nipa awon isele ohun ti o ti koja, ohun ti nsele lowolowo ati ohun ti nbo wa sele fun o, tabi ki o fi han o.

Ti o ba fe mo asiri Oluwa, beru re, ki o si ni idapo pelu Olorun. Nigbana ni yio fi o mo majemu re, ti yio si fi idi majemu re mule ninu aiye re **Orin Dafidi 25: 14**. Ti o ba je olotito si Oluwa, ti o si ni idapo pelu re; Oluwa yio fi oye asiri agbara ati ogo orun ye o; pataki-julo, bi o ti se le lo agbara-Olorun lati pa ijoba Satani run; ti Esu yio si di itemole labe ese re. Siwajusi Oluwa yio fi idi majemu re mule ninu aiye re ati ninu aiye aromo-domo re lehin re.

Enia eleran-ara bi tire ni Mose, a si fun ni ore-ofe lati ba Olorun soro ni ojukoju. Olodumare le fun iwo na ni iru ore-ofe yi, tabi eyiti o tun dara ju ore-ofe yi lo, bi o ba ni idapo pelu re **Eksodu 33:11.** Ti o ba feki Olorun fun o ni ore-ofe iru eyiti ko ti sele ri, ninu iran baba-nla re, ni idapo pelu Olorun.

**Ohun-elo ododo ti o wulo:** Ti o ba ni idapo pelu Oluwa, yio se o ni ohun-elo ododo ti o si wulo fun itan-kale ihinrere; ti iwo yio si ma jere okan sinu ijoba re. Oluwa lo Paulu aposteli lati fi oye ye gbogbo enia, ohun ti ise-iriju ohun ijinle na jasi eyiti a ti pamo lati aiyeraye ninu Olorun, eniti o da ohun gbogbo nipa Jesu Kristi **Efesu 3: 8-9**. Ti o ba ni idapo pelu Olorun, o le yan o, lati salaye siwaju si, aditu-ipinnu ti o ni fun awa eda-enia. Ti iwo yio si so fun araiye awon ere ti o wa ninu asiri ti Olorun ti fi pamo lati ibere-pepe, ki awon enia ba le wa Oluwa Olorun won pelu gbogbo ipa won.

**Ore mi ni o nse:** Enikeni ti o nfe wa lara awon omo tabi ore Oluwa ni lati ti oju re si ifekufe aiye yi. Awon enia be ni lati ni idapo pelu Olorun, ki won si gboran si lenu **Johannu 15: 14**. Bi o ba fe je okan lara awon kosemani ore Kristi, se ohun gbogbo ti o palase fun o.

## Awon apejuwe ninu Bibeli

Ao mu ninu awon enia ti won ni idapo pelu Olorun ninu bibeli lati fi se apejuwe, besini ao se ayewo ni finifini bi Olorun ti se lo won,ti o si fun won ni ere ise won.

**Josua:** Lehin iku Mose Olorun beresini gbe Josua ga li oju gbogbo Israeli. Gbogbo enia si mo wipe Olorun wa pelu Josua gegebi o ti wa pelu Mose ni igba aiye re.
Olorun pin odo Jodani niya (omi ti nti oke san wa duro, o si ga bi okiti) fun awon omo Israeli lati koja li iyangbe ile, gegebi o ti pin Okun-pupa niya ni igba aiye Mose **Josua 3: 5-13**.

Nigbati Josua siwaju awon omo Israeli lati ba Adoni-sedeki oba Jerusalemu, Hohamu oba Hebroni, Piramu oba Jarmutu, Jafia oba Lakisi ati Debiri oba Egloni jagun. Olorun se ohun-ara kan nigbati Josua wipe " iwo oorun duro je lori Gibeoni; ati iwo osupa ni afonifoji Aijaloni ". Oorun duro je kosi yara lati wo, besini osupa duro je ninu ipa ona re, titi awon enia fi gbesan lara awon ota won **Josha 10: 12-14**. Ohun ti o sele ni ojo-nla yi, si nsele ninu aiye titi di oni oloni, awon olugbe iha guusu ati ariwa ma nri ifarahan isele ojo-nla yi ni ekan larin odun.

**Danieli:** Oluwa gba Danieli sile lowo awon kiniun, nigbati oba pase pe ki a so sinu iho kiniun. Oluwa gba sile nitori idapo re pelu Olorun. **Danieli 6: 10-24**.

**Awon enia Juda:** Awon enia Juda ni idapo pelu Olorun nipa orin iyin, eyi ni o mu ki Oluwa yan ogun-ehin si awon omo Ammoni, Moabu ati awon ara oke Seiri ti o wa si Juda, a si kolu won **2 Kronika 20: 18-23**.

**Hanna:** Oluwa bukun fun Hanna pelu awon eso-inu, nigbati o ni idapo pelu Olorun ni tempili ti nbe ni Silo **1 Samueli 1: 9-17**.

**Elijah:** Nigbati ogbe-ile wa gegebi asotele Elijah, o lo si Sarefati, nibiti o ti ri opo kan, o si bere ohun jije ati mimu lowo re. Obinrin opo yi fun ni ohun jije ati mimu, besini Elijah sure fun eleyi wipe " ikoko iyefun re ki yio sofo, beni kolobo ororo re ki yio gbe, titi di ojo ti Oluwa yio ro ojo si ori ile. " Oro ti Elijah so wasi imuse nitoripe o ni idapo pelu Olorun **1 Awon oba 17: 10-16**.
Olorun tun lo Elijah lati ji oku omo obinrin opo yi dide **1 Awon oba 17: 17-23**.

**Awon Aposteli:** Awon aposteli ni idapo pelu Olorun, orisirisi ise iyanu ni o sele nipase won. Olorun ti owo awon aposteli se ise ami ati ise iyanu pupo larin awon enia **Ise awon aposteli 2: 43, 5: 12**. Bi a ba je eniti o nka bibeli, ao ri wipe ise iyanu ti a kole ka tan, ni o ti owo awon aposteli sele **Ise awon aposteli 14: 3**.

**Iyasimimo Tempili:** Ni ibi iyasimimo tempili ti nbe ni Jerusalemu, nigbati a gbe apoti-eri Oluwa wa si ipo re, ti awon omo Lefi si nfi awon ohun-elo orin yin Oluwa. Awosanmo kun inu tempili na, tobe ti awon alufa ko le duro lati sise isin nitori awosanmo na: nitori ogo Oluwa kun inu tempili na **2 Kronika 5: 11-14**.

# Christ Apostolic Miracle Ministry Sunday School

**Ose Kerindinlogoji: Osu Kesan Ojo Kerin, 2016**

**Akori Oro: Idapo pelu Olorun** – Apa keta

**Eko kika: 2 Korinti 6: 11-16**

Ni ikorita yi bi a kuna lati menuba idapo pelu awon enia mimo, idapo pelu Emi Mimo ati idapo pelu Jesu Kristi; a je wipe eko yi kise kikun, nitoripe awon idapo ti a ka sile yi won fi ara yi idapo pelu Olorun, won wonu ara won, besini won so-po pelu idapo pelu Olorun.

**Idapo pelu awon enia mimo**

Idapo pelu awon enia mimo je ojuse awa Kristiani atipe a ni lati tele liana yi, ki a ba le ni idapo pelu Olorun. Bi a ko ba ni idapo pelu awon asoju-Olorun ti won je enia eleran-ara gegebi awa tikara wa, bawo ni ao tise ni idapo pelu Olorun ti nse Emi, ti a ko si fi oju ri.
Ni igbakugba ti a ba ni idapo pelu awon enia Olorun, nse ni a nhun ni idapo pelu Olorun. Idi re niyi ti Johannu fi wipe "Eyiti awa ti ri, ti awa si ti gbo li awa nso fun nyin, ki enyin pelu ki o le ni idapo pelu wa: nitoto idapo wa si nbe pelu Baba, ati pelu Omo re Jesu Kristi " **1 Johannu 1: 3**. Iwo na gba awon enia niyanju, ki o si se ohun iwuri, ti yio muki won ni idapo pelu awon eni-mimo; ki a ba le fi idi idapo won pelu Olorun mule. Kede wipe nigbati won ba ni idapo pelu awon eni-mimo, nigbana ni won ni idapo pelu Baba ati Omo re Jesu Kristi. Ranti wipe a ko gbodo ko ipejopo awon enia mimo sile **Heberu 10: 25**.

**Gbadura fun awon eni mimo:** O le ni idapo pelu awon eni-mimo nipa gbigba adura fun awon olufokansin. Gba adura fun won ni igbagbogbo, pataki-julo ma dupe lowo Oluwa lori gbogbo onigbagbo agbaiye. Ma bere ohun ti o dara ninu adura fun awon eni-mimo, nitori idapo tiitan Ihin-rere kakiri origun mererin aiye **Filippi 1: 3-5**. Mase je oni imo tara-eni nikan, ni idapo, ki o si gba adura kikan lai-sinmi fun awon eni-mimo; nitori gbogbo laala didasi ati fifi ara mo itankale Ihin-rere ti Kristi titi di isinsinyi.

**Je alafehinti fun awon mimo:** A gba Paulu ati Barnaba gegebi olubasise-po ninu ogba ajara Oluwa. Awon aposteli gba won niyanju lati lo waasu fun awon keferi, nigbati awon yio si tesiwaju ninu ise won larin awon onila **Galatia 2: 9**. Na owo otun idapo jade, nipa sise ise ninu ifimo-sokan pelu awon eni-mimo, je

eniti o nfi owo ti won-lehin ki won ba le se aseyori ninu ise-iranse won.

**Fifun awon mimo tokantokan:** O le ni idapo pelu awon eni-mimo nipa pipese ohun ti o ye fun won, ki aini won ba le di itan; ni ona ti yio jeki won fi gbogbo ipa ati agbara won sise laisi iberu tabi ikominu. Paulu gbe osuba fun awon ara Makedonia, toripe won nfi ebe ro wipe ki o gba ebun lati pin fun awon enia mimo; ki awon na ba le ni ipin ninu idapo pelu awon eni-mimo ti nbe ni Jerusalemu. E jowo, e jeki a lo ogbon wa, oro wa, akoko wa ati akitiyan wa lati bojuto aini awon eni-mimo; ki o ba le dara fun wa **2 korinti 8: 4**. Mase kuna lati darapo ninu ohunkohun ti yio mu itura ba awon eni-mimo, ki o si ma pese ohun ti won nilo laisi idaduro. E jeki a se afarawe awon ara Makedonia nipa ipin-funni awon ola wa; ki a si lo akoko ati imo wa fun onigbagbo agbaiye.

## Idapo pelu Emi Mimo

O se pataki, o se koko, o leto, besini o ye lati ni idapo pelu Emi Mimo. Ranti wipe emi ni Olorun, nigbati awa enia si je ara, nitorina a nilo iranlowo Emi Mimo lati darapo ninu emi pelu Olorun. Bibeli wipe a ni lati wa itunu, isipe-ife ati idapo ti Emi Mimo nipase Jesu Kristi **Filippi 2: 1**. Ni iwon igbati o je wipe Emi Olorun ni o so wa di okan, e jeki a tesiwaju ninu idapo ti a ri pin ninu Emi, ni aiyese.
A ni lati mo wipe Emi Mimo ni o nran ailera wa lowo; nitori a ko mo bi a ti igbadura gege bi o ti ye: sugbon Emi tikarare nfi irora ti a ko le fi enu so bebe fun wa **Romu 8: 26**. Nitorina mase ko idapo Emi Mimo sile.

## Idapo pelu Kristi

Jesu Kristi wipe "Emi li ona, ati otito ati iye: ko si enikeni ti o le wa sodo Baba, bikose nipase mi ". Eyi tumo si wipe enikeni kole ni idapo pelu Baba wa ti nbe ni orun bikosepe ki o koko ni idapo pelu on Omo re **Johannu 14: 6**. Ri dajupe o ni idapo pelu Kristi, ki idapo re pelu Olorun ba le se itewogba.

**Olorun je olododo:** Nitori Olorun je olododo ni o jeki o pe wa sinu idapo Omo re Jesu Kristi Oluwa wa **1 Korinti 1: 9**. Kise nipa ipa tabi agbara, sugbon nipa ododo Olorun ni o jeki o sese lati ni idapo pelu Jesu Kristi Omo re. Torina mase si ore-ofe yi lo.

**Ara Kristi ni iwo nse:** Awa onigbagbo ni ara Kristi, olukuluku wa si je eya ara

re. Torina lo ago-ara re ti nse eya-ara Kristi fun idapo pelu re **1 Korinti 12:27.** Niwon igbati gbogbo wa lapapo je ara Kristi, ti olukuluku wa si je eya-ara re, e jeki a jo sise papo nipase idapo lati jeki ara Kristi ni alafia pipe.

**Ni ipin ninu ijiya Kristi:** Onigbagbo ni lati ju awon ifekufe aiye yi sile, ki won si kehin si i, ki won ba le mo Kristi ati agbara ajinde re, ati alabapin tabi ni idapo ninu iya re; nigbati won ba faramo iku re **Filippi 3: 10**. Okan ninu awon ona ti o daraju lati ni idapo pelu Kristi ni ki enia o se alabapin ninu ijiya re, ki o le dabi Kristi nigbati o ba ku.

**Orun ni ilu-ibile re:** Awa olufokansin kise alejo ati atipo mo, sugbon ajumo je oloto pelu awon enia mimo ati awon ara ile Olorun **Efesu 2:19**. Fi idi idapo re pelu Kristi mule loni, ki a ba le ka o ye gegebi omo onilu ni orun.

## Idapo Mimo tabi Onje ale Oluwa

Idapo mimo je majemu-idapo ti Olorun gbe kale nipase Jesu Kristi Oluwa wa. Eyi je majemu aiyeraye ti o so wa po mo Kristi, ti o si so wa di okan pelu re laialai, niwon igbati a ba ti tele ofin idapo-mimo. Ni igbakugba ti a ba nipa ninu idapo-mimo, a nso wa po pelu ara ati eje Kristi pelu majemu aiyeraye.

**Kristi odo-aguntan irubo wa:** Jesu Kristi ni odo-aguntan Olorun, eniti o ko ese araiye lo **Johannu 1: 29, 36**. Kristi yi ni odo-aguntan irekoja, ti a fi rubo ki awa ki o le wa laaye. Nitorina, e mu awon enia buburu kuro ni arin yin, ki e si kuro ninu ninu awon iwa-atijo yin, ki e ba le di iyefun titun **1 Korinti 5: 7**. O di dandan ki e ni idapo pelu Kristi, irekoja wa, ti a fi rubo fun wa.

**Ara ati eje Kristi:** Idapo mimo je idapo ti a ni pelu ara ati eje jesu Kristi Oluwa wa. Iwe mimo wipe "ago ibukun ti awa nsure si, idapo eje Kristi ko ise? Akara ti awa nbu, idapo ara Kristi ko ise? " **1 Korinti 10:16**. Ni kukuru, idapo-mimo je idapo pelu eje ati ara jesu Kristi. Torina lehin ti e ba ti kopa ninu idapo-mimo, enikeni ti o ba kolu wa, ti kolu Jesu Kristi.

# Christ Apostolic Miracle Ministry Sunday School

## Igbekale idapo mimo

Jesu mu akara o si sure, o si bu, o si fifun awon omo-ehin re, o si wipe , “gba je; eyiyi li ara mi. O si mu ago, o dupe, o si fifun won wipe, gbogbo nyin e mu ninu re. Nitori eyi li eje mi ti majemu titun, ti a ta sile fun opo enia fun imukuro ese” **Matteu 26: 26-28**.

**Aye fun jije idapo mimo:** Ibi aye ti a ti le je onje ale Oluwa ni ninu tempili Oluwa, o si ni lati je iwaju, ni itosi pepe Oluwa. Bibeli fi idi re mule wipe “ awa ti ise opololpo jasi akara kan: nitoripe gbogbo wa li a jumo npin ninu akara kan ni. E wo Israeli nipa ti ara: awon ti nje ohun ebo, nwon ki ha ise alabapin pepe?” **1 Korinti 10: 17-18**. Niwon igbati awon omo Israeli ti fi apere yi le ile, nigbati won nfi isokan je ebo won nibi pepe. Torina mase je onje ale Oluwa ni awon ibiti ao daruko wonyi: **Ile Iwosan, ninu ile re, ninu tubu tabi ogba ewon, ni ita-gbangba tabi ibomiran, bikose ninu tempili,** ki o ba le se itewogba si Oluwa.

**Iwa wiwu ni tabili Oluwa:** O ni awon iwa ti a gbodo wu ni tabili Oluwa ki idapo mimo wa ba le se itewogba si Olorun. Gbogbo enia ni lati je onje ale Oluwa lapapo, laisi wipe onikaluku nje tire ni oto-to. Paulu aposteli gba awon ara Korinti ni imoran wipe nigbati won ba pejo lati jeun ale Oluwa, e ma duro de ara nyin **1 Korinti 11: 33-34**. Bi e ko ba duro de ara yin, ki ipejo fun idapo-mimo yin maba di idajo lori yin, torina mo iwon ara re. Atipe e ma se ohun gbogbo teyeteye ati leselese **1 Korinti 14: 40**.

A ko sinu bibeli wipe Olorun ki ise Olorun  ohun rudurudu, sugbon ti alafia, gege bi o ti je ninu gbogbo ijo enia mimo **1 Korinti 14: 33**. Nitorina, ti e ba pejo lati je onje ale Oluwa, e se ohun gbogbo pelu owo, irele ati iteriba. Jeki okan re wa niwaju Oluwa, masi se fi aye gba agabagebe tabi ohunkohun ti o le mu idarudapo ati rudurudu wa sinu ipejopo **1 Korinti 11: 20-22**.

## Christ Apostolic Miracle Ministry Sunday School

**Ose Ketadinlogoji: Osu Kesan Ojo Kokanla, 2016**

**Akori oro: Idapo pelu Olorun** – Apa kerin

**Eko kika: 2 Korinti 6: 11-16**

Ao tesiwaju ninu eko wa, nigbati ao bere pelu awon ire ati idajo ti o diromo ki enia ni ipin ninu onje ale Oluwa.

### Awon ire ati idajo idapo

Bi enia ba ni ipin ninu idapo mimo ti a se ni ona ti o to, opolopo ore ni yio sawari aiye iru okan be: Sugbon ti enia ba se ajopin pelu okan idoti ati eri-okan ti ko mo, onitohun ni yio ru ebi re. Ni ikorita yi, mo fe ki a mo wipe emi ti o ba wa ninu aiye enia nigbati o ba ko'pa ninu idapo mimo, ni onje ale Oluwa yi yio ru soke; yala Emi mimo ni tabi emi-aimo.

**Ise iranse Paulu aposteli ni Troa:** Ni ojo kini ose, awon omo-ehin pelu Paulu pejo lati je onje ale Oluwa. Isele kan sele sugbon Paulu bori, nitoripe o ti mura sile pelu okan mimo ati eri-okan rere lati je onje ale Oluwa. Emi mimo ti ngbe inu Paulu ki o to je onje ale Oluwa ru soke, tobe ti o fi le ji oku Eutiku dide, eniti o di ologbe nipase ifarapa ati ogbe ti o ni nigbati o subu lule; lati oju ferese ti o joko si ni oke keta **Ise awon aposteli 20: 7-12**.

**Judasi Iskariotu:** Satani wo inu Judasi Iskariotu, nitori ife ti o ni si owo. Eleyi lo ba olori alufa ati awon olori eso, nipa bi yio ti fi Kristi le won lowo. Inu nwon dun, nwon si yo, nwon ba Judasi da majemu ati fun u ni owo ki o le da'le Jesu **Luku 22: 3-6**. Lehin igbati nwon je onje ale Oluwa tan, ti Esu si fi si okan Judasi lati fi Oluwa han **Johannu 13: 2**. A ni lati mo wipe, nigbati won nje onje ale okan Judasi kun fun emi-odale ti nse emi buburu. Lesekese lehin ti o je onje ale Oluwa tan, emi aimo yi ru soke; o si to olori alufa ati awon toku lo lati fi Jesu han **Johannu 13: 27-30**. Ko eko lara isubu Judasi, ki o ma ya ara ati okan re si mimo pelu eri-okan rere ki o to ko'pa ninu idapo mimo.

### Mase ni idapo pelu okunkun

Paulu aposteli se ikilo wipe "e mase fi aidogba dapo pelu awon alaigbagbo: nitori idapo kini ododo ni pelu aisododo? Idapo kini imole si ni pelu

okunkun?" **2 Korinti 6: 14**. A ti ki o nilo wipe ki o sora, nitorina kiyesara, toripe ko si ajosepo larin ire ati ibi. Niwon igbati o je wipe kosi idapo larin imole ati okunkun, ti kosi si ifowosowopo larin ododo ati aburu; mase ni idapo pelu okunkun.

Ara mi, e mase ba aileso ise okunkun kegbe po, sugbon e kuku ma ba won wi. E mase ko ipa ninu aileso ise okunkun tabi tiwon lehin, besini e ko gbodo gbe ori-yin fun won; sugbon e ma ba won wi, ki e si ma tu won ni asiri **Efesu 5: 11**. E mase ko ipa ninu ainilari ise ibi tabi ise okunkun, e mase se iranlowo nipa owo tabi akitiyan fun won; sugbon e ma tu won ni asiri ni gbogbo igba.

Nigbati awon keferi ba nrubo, nwon nrubo si awon emi esu kise si Olorun, nitorina mase se ajopin tabi gba ninu awon ohun ti a fi rubo; ki o maba ni idapo pelu awon ebora ati alujonnu **1 Korinti 10: 20.** Ti o ko ba fe ni idapo pelu awon emi esu tabi okunkun mase ko'pa tabi je ninu awon ohun ti a ba fi rubo si orisa.

## Wadi ara re ki o to kopa ninu idapo

Onikaluku ni lati se ayewo ara won, bi won ba ri wipe awon ye tabi yege, igba na ni ki won to darapo, ki won si ni ipin ninu idapo mimo.

**Se iwadi ara re:** Imoran mi fun gbogbo onigbagbo ti won ko feki idajo Oluwa wa sori won, ni wipe, ki won ye ara won wo ; ki won to ko'pa ninu idapo mimo. Paulu na gba wa ni imoran wipe "ki enia ki o wadi ara re daju, beni ki o je ninu akara na, ki o si mu ninu ago na" **1 Korinti 11: 28**. Se iwadi eri-okan re lati mo boya ohun ti o nse wa ni ibamu pelu awon ofin ti o diromo jijeun ni tabili Oluwa. Ri daju pe o ni iwa ti o ye, ki o to se ajopin ninu idapo mimo. Siwajusi, bi a ba se ayewo ara wa ti a si wadi ara wa pelu otito; ti a jewo awon asise wa ti asi se igbese lati se atunse awon iwa yi, Olorun ki yio da wa lejo **1 Korinti 11: 31**. Arakunrin ati arabinrin, se iwadi ara re ni finifini ki o le mo ibiti o ku si; ki o si le se atunse ki o to ko'pa ninu idapo, ki Oluwa maba da o lejo.

**O ko gbodo se ajopin ni tabili emi esu:** Sa fun gbogbo ohun ti nse iborisa. Mase nipa, mase kopa, mase iranlowo tabi atilehin fun iborisa. Bibeli wipe " enyin ko le mu ago Oluwa ati ago awon emi esu: enyin ko le se ajopin ni tabili Oluwa, ati ni tabili awon emi esu" **1 Korinti 10: 21**. A ti fi oye ye o, osi ni lati mu okan ninu mejeji; boya Olorun ni o fe ni idapo pelu ni tabi Esu. Mo gbadura ki o le mu eyiti o dara. Nitoripe "ko si eniti o le sin oluwa meji: nitori yala yio korira okan, yio si fe ekeji; tabi yio faramo okan yio si yan ekeji ni iposi. Enyin ko le sin Olorun pelu mammoni" **Matteu 6: 24**.

**<u>Se ajopin ni tabili Oluwa nikan:</u>** Awon aposteli se ajopin ni tabili Oluwa, besini awon enia ri ayipada nla ninu aiye won. A ri ayipada nipa ti agbara orun ati ogo Olorun ni arin won, debipe idagbasoke wa ninu ijo won, ti alafia Olorun si joba ninu aiye won **<u>Ise awon aposteli 2: 40-42</u>**. Iwo na le ni iru ore-ofe yi ninu aiye re, bi o ba se ajopin ni tabili Oluwa; ti o si se gegebi igbekale liana idapo mimo.

## <u>Mase je onje Oluwa laiye</u>

Mo ntenumo wipe, enikeni ti o ba je akara, ti o si mu ago Oluwa laiye; yio jebi ara ati eje Oluwa **<u>1 Korinti 11: 27</u>**. Niwon igbati Olorun ki ise enia ti yio fi seke, tabi ki o fi igba kan bokan ninu, enikeni ti o ba ko'pa ninu idapo laiye, ni ao da lebi ara ati eje Oluwa.

**<u>O le jasi idajo, aisan tabi iku:</u>** A ni lati mo ninu okan wa pe "bi enia ba momo dese lehin igbati o ba ti gba imo otito, ko tun si ebo fun ese mo;" bikose ireti idajo ti o bani leru, ati ti ibinu ti o muna, ti yio pa awon ota Olorun run **<u>Heberu 10: 26-27</u>**.
Nitorina, enikeni ti o ba nje, ti o si nmu laimo ara Oluwa yato; o nje o si nmu ebi fun ara re **<u>1 Korinti 11: 29</u>**. Ti o ko ba feki idajo Olorun wasi ori re, jeki emi re dogba pelu Oluwa nigbakugba ti o ba nko'pa ninu idapo mimo.
Ebi ti o wa ninu jije akara ati mimu ago laiye ko mo ni idajo Oluwa nikan, ole fa ailera tabi aisan tabi iku. Paulu jeri si oro yi, nigbati o wipe "nitori idi eyi ni opolopo ninu nyin se di alailera ati olokunrun, ti opolopo si sun" **<u>1 Korinti 11: 30</u>**. Ti o ko ba fe ailera tabi aisan tabi ki o ku lai-tojo, mase je onje ale Oluwa laiye.

## <u>Ofin iranti</u>

Jesu Kristi ni igba aiye re pa wa lase, wipe ki a ma kopa nigba gbogbo ninu onje ale ni iranti On. Torina, onigbagbo ti ko ba ni ipin tabi ko'pa ninu idapo mimo ti se aigboran si ase Jesu Kristi Oluwa wa **<u>Luku 22: 19, 1 Korinti 11: 24-25</u>**. Ranti wipe bi o ko ba ko'pa ninu idapo mimo, o ko ni ipin ninu Kristi besini Jesu na ko ni ipin ninu re. E jeki o di mimo fun wa pe kosi alaigboran kan ti yio wo ijoba Olorun.

## E kede iku Oluwa

Nigbakugba ti a ba nje akara, ti a si nmu ago ni tabili Oluwa; ise ni a nkede iku Oluwa titi yio fi pada wa sinu aiye **1 Korinti 11: 26**. Tesiwaju ninu ikede re si araiye wipe, Oluwa ku nitori ki o le rawapada ni; nipa kiko'pa ninu onje ale Oluwa: atipe Oluwa si npadabo lati mu awon ayanfe re'le.

**Edidi: 2 Korinti 13: 14:** Ore-ofe Jesu Kristi Oluwa, ati ife Olorun, ati idapo ti Emi mimo, ki o wa pelu gbogbo nyin. Amin.